E MA KA

IROHIN IMOLE

KI E SI MA POLOWO OJA YIN SINU RE. O kun fun irohin aladun, o si nkọ enia ni ẹkọ dada. O nfun enia ni oye.

# IRỌHIN IMỌLẸ

MOTTO: IMỌLẸ DE, OKUNKUN PARADA.

AKIYESI

E ma ka iwe Irohin Imọle nigbagbogbo nitoripe itan aladun mẹta kan yio bẹrẹ ninu rẹ laipẹ yi. Ekini ni itan Kọgbọn ninu eyi, orire ọmọ-ubẹ lọwọ iya rẹ (apakini) itan igbesi aiye awọn ayaba ati awọn ologbọn aiye (apakeji) itan igbesi aiye awọn ọrẹ meji oni-jibiti Eko ati Olọṣa Ilorin (apakẹta)

VOL. I No. 29, WEDNESDAY 15, JANUARY – JANUARY. 21, 1958 KỌBỌ KAN

# SALISU LAWANI FE JI OMO KAN GBE

YABA

Agbo irohin bayi wipe, omode obinrin kan ti o ti tele iya re lo si oja ni Yaba wa npada lo sile, omo na to odun mejila, bi o ti nlo, beni o pade Salisu Lawani.

Nigbati Salisu wo ọtun, wo osi, ti ko ri ẹnikan, o da ọmọ na duro, o si nbere lọwọ ọmọ na wipe, njẹ iwọ kọ ni o njẹ Sisi? ọmọ na si dahun pe nda o, ko nṣe on. Salisu ni ki o kalọ gba kobọ.

Bi Salisu ti nfa ọmọ na wọ inu igbo lọ, bẹni ẹnikan ti o nbọ ri i, o bẹrẹsi kebosi pe, o ngbe ọmọlọmọ wọ inu igbo lọ, gbogbo enia dide, nwọn mu Salisu, nwọn si gba ọmọ na kuro lọwọ rẹ, nwọn fa le Ọlọpa lọwọ.

Lojọ keji nigbati ọrọ na de iwaju adajọ, awọn Ọlọpa bẹrẹsi ka ẹṣẹ ti Salisu ṣe niwaju rẹ, nṣe ni a gbọ wipe Salisu bu si ẹrin gbaragada tọbẹ ti Adajọ fi kilọ fun pe on ko gbọdọ tun ri iru rẹ mọ. Nigbana ni Adajọ yẹ ẹjọ si rẹ ọjọ Jimọ ti iṣe ọjọ kẹtadinlogun oṣu yi (17th January 1958) o si kọ lati gba iduro fun Salisu, a gbọ pe oju rẹ ti ranko.

E ma ka Iwe Irohin Imole

## Akorin Yi Yio Sere Ni Ile Eko Giga Ti King's College

Oje nkan ti o ṣe ọwọn pe ki awọn ti ntẹ duru ni ibi iworan ma wa si igboro eko, ṣugbọn arabinrin Phillippa Schuyler ara Amẹrika ti nrin ajo kakiri ilu Oyinbo ati ti enia dud, yio fi ibẹwo rẹ ṣe wa lẹyẹ. A bi arabinrin yi ni New York City ni ọdn 1932 Lati igbana kekere ni o ti nṣe ẹnu ṣamuṣamu nipa di da orin kọ, ti o si tun nṣe nkan ribiribi lọna yi.



OMIDAN SCHUYLER

Lẹhin eyi a fun ni orisirisi ẹbun nipa aṣeyọri rẹ yi. Nigbati o di ọmọ ọdun mẹrinla o bẹrẹ si kọrin pẹlu awọn ẹgbẹ onilu kan ni New York, ki o to rin irinajo rẹ akọkọ kakiri ilu Oyinbo ni 1953, o kọ nipa orin gan. Yio si ya leko bẹlu gbogbo olẹ rẹ lọna irin ajo rẹ si Sudan ati Ghana.

Ninu ẹro ẹiran ti awọn Lagos Musical Society nṣe eto rẹ yi, ti a o si se ni Kings College ni aṣalẹ oni yi.

Obinrin yi yio ṣe orisirisi ere bi ti owọn enia jankanjankan bi Scorlatti, Gershwin, John Field, Ghopin. Yio si fi ẹnu ba diẹ ninu ere ti Ravel de Fella ati awọn ẹlomiran. A si tun ro wipe a o yi arabinrin yi lọkan pada ki o si tẹ orin ti o kọ funra rẹ lori duru.

Eto ọjọ oni yio gun gbọrọgbọrọ bi ọpa ibọn, yio si tun gba akoko pupọ. A o si gbadun rẹ pupọ, inu awọn ara Eko yio si dun nwọn yio si dupẹ fun anfani ti nwọn ni lati fi tẹti si obinrin yi.

Lẹhin na yio bẹ ilu Jos wo, yio si ṣe iru nkan ti o ba ṣe ni Eko ni ibẹ ni ọjọ kẹtadinlogun oṣu Ṣẹrẹ. Ọgbẹni Kọla Balogun lati ayagrẹ ni o gba obinrin yi tọwọ tẹṣe ni Eko-

## SHOYINKA TUN GBE DE

Turari fun Arisiki lati ilẹ India 10/6d
Iwe Adura Akanse 3/6d
Iwe Ilana Esin Ojisẹ nla Muhammad 7/6d
Kurani Esumẹta ti a tumọ si Yoruba 10/6d
Odu mẹrindinlogun 10/6d
Iwe Aniyan ati Nofila Oru Oṣu Awẹ 5/6d
Iwe Egbogi Ajẹbidan 20/-
Itan Aladun 3/-
Gbedegbẹyọ Hausa 3/-
Ajiran Ilu Oku 3/-
Itumọ ala kikun 5/6d
Iwe Owe Yoruba 3/6d
Psalmu Isẹgun Ajẹ ati aiye 17/6d pẹlu Turari lọfẹ
Turari Itaja 10/6d
Turari Eyọnu Ajẹ 10/6d
Abẹla Adura (Dragon Candle) fun Adura tete Dami lohun 15/-6d

Fi owo ransẹ si:-
J.O. SHOYINKA c/o Post Office Ebute Mẹtta Tabi
8, Ojo Road (Oduabọrẹ) Mushin.

## Akawo (Cashier) Mohmudu

DANTATA SE AIYEDERU

Kano

**Mohmudu Dantata ti o nse omo ologbe Alasan Dantata. olowoarakuyamo kan nigboro ilu Kano** ẹniti awọn ọlọpa ba ṣe ẹjọ wipe nwọn ri owo aiyederu lọwọ rẹ ti nwọn si gbe ju sewọn, lo pe Akawo (Cashier) lẹjọ siwaju Alikali agba ni Kano pe, on lo ṣe okunfa ti owo bi £2350 fi pora ninu iṣẹ owo on ti a npe ni West Afrikan Pilgrim Association.

